# IDALARE NIPA IGBAGBỌ́

**Romu 8:1-39**

**ẸKỌ 353 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: “Bi Ọlọrun bá wà fun wa, tani yio kọ oju ija si wa?” (Romu 8:31).**

### Idalẹbi fun Ẹṣẹ

Paulu le sọ pẹlu gbogbo ọkàn rẹ pe, “Njẹ ẹbi kò si nisisiyi fun awọn ti o wà ninu Kristi Jesu.” Jesu ti dá a nide kuro ninu ẹ̀ṣẹ, O si jẹ́ Oluwa rẹ̀.

Idalẹbi ọkàn ni o n mu ki ara eniyan kó tiọ, ki oju ki o ti i, tabi ki o ni ẹbi ẹ̀ṣẹ ninu ọkàn fun iṣe buburu tabi nitori ọ̀rọ aidara ti o sọ. Gẹgẹ bi iṣudẹdẹ ikuukuu ti i tàn ká oju-ọrun ti si i bo oorun, bẹẹ gẹgẹ ni iṣudẹdẹ idalẹbi n tàn bo ojú ọkàn eniyan, a si pa oju Ọlọrun mọ́ nigba ti ẹni naa bá dá ẹ̀ṣẹ. Iyọ́nú Ọlọrun kò si lori ẹni naa; itanṣan ogo Ọlọrun kò si si ninu ọkàn naa. Ṣugbọn idalẹbi a maa bo ọkàn yii bi ikuukuu ti o nipọn. Irisi oju eniyan paapaa a maa saba fi idalẹbi ti o wà ninu ọkàn hàn.

Ṣugbọn nigba ti ẹni naa bá wá Ọlọrun bi o ba si ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ti o si ri idariji ẹ̀ṣẹ gbà, ati ti o tọrọ idariji lọwọ awọn wọnni ti o ti ṣẹ̀, gbogbo idalẹbi yoo kuro ninu ọkan rẹ̀, yoo si bọ́ lọwọ ẹbi ẹ̀ṣẹ. Nigba naa ni yoo le wi pe kò si idalẹbi mọ́ nisisiyii.

Nigba kan ri Paulu ni idalẹbi nla ninu ọkàn rẹ̀. Satani ni o n ṣe oluwa rẹ̀, Paulu si n gbọran si i lẹnu pẹlu. Nigba ti ẹni ibi ni ba sọ fun Paulu pe ki o ṣe inunibini si awọn eniyan Ọlọrun, ki o dè wọn ki o si fi wọn sinu tubu, oun a si ṣe bẹẹ. Ṣugbọn gbogbo iwọnyi ni o yi pada ninu igbesi-ayé Paulu lọjọ naa ti o pade Jesu ni ọ̀na Damasku. Wo bi itanṣan imọlẹ naa ti mọlẹ tó lori rẹ̀ ati bi iṣudẹdẹ òkunkun ti o bò ó mọlẹ ti tó ni oju ọ̀na rẹ̀ si ilu Damasku! Wo bi idalẹbi yii ti le jinlẹ tó ninu ọkàn Paulu nigba ti o wá ye e pe Jesu ti Nasarẹti ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ni oun n pa lara! O ba a ninu jẹ́ -- ani lọpọlọpọ; o bẹ Jesu pe ki O dariji oun. Nigba ti Paulu ri igbala, gbogbo idalẹbi ni o kuro ninu ọkàn rẹ̀. Bi ipẹ́pẹ ti n bọ́ kuro ni oju rẹ̀, o riran, lẹsẹkẹsẹ Paulu bẹrẹ si i ṣiṣẹ fun Jesu Kristi, Ẹni ti i ṣe Oluwa rẹ̀ titun.

### Oluwa Meji

“Ko si ẹniti o le sin oluwa meji” (Matteu 6:24). Ẹni kọọkan ni o n sin Kristi tabi Satani. O ṣe e ṣe ki eniyan paarọ̀ oluwa ti o n sin, ohun ti Paulu ṣe gan an ni yii.

O le beere, “Bawo ni emi ṣe le ni Kristi bi Oluwa mi?” Lọna kukuru, nipa gbigba adura atọkanwa si Ọlọrun, ni bi bẹ Ẹ pe ki O dari awọn ẹ̀ṣẹ rẹ ji ọ, ati ni sisọ fun Un pe iwọ yoo sin In. A kà ninu Ọrọ Rẹ̀ pe, “Ẹniti o ba si tọ̀ mi wá, emi ki yio ta a nù, bi o ti wù ki o ri” (Johannu 6:37). Nigba ti Ẹjẹ Jesu ba bo ọkàn rẹ, gbogbo ẹ̀ṣẹ rẹ ni a o fi ji; iwọ yoo si ni inudidun ati ominira. A o mú idalẹbi kuro ninu ọkàn, iwọ yoo si ni agbára maa lọ má dẹṣẹ mọ́. Ibẹrẹ igbesi-ayé titun! Ọkàn titun! Oluwa ọ̀tun lati sìn! “Njẹ bi a si ti nda wa lare nipa igbagbọ́, awa ni alafia lọdọ Ọlọrun nipa Oluwa wa Jesu Kristi” (Romu 5:1).

### Ewu ti o wà ninu Ẹṣẹ

Oluwa onroro ni Satani jẹ́ fun eniyan lati sin. A maa ṣeleri inudidun, ilera, ọrọ̀ ati iye; ṣugbọn a maa fi ijatilẹ̀, aisan, oṣi ati ikú rọpo wọn. Ma ṣe tọwọ bọ ẹ̀ṣẹ; máṣe rò pe o le fi ibi ṣiré. Ma ṣe rò pe iwọ le jẹ igbadun awọn ẹ̀ṣẹ wọnni ti o dabi ẹni pe o kere diẹ pẹlu “faaji ailewu” wọn, ṣugbọn lai pẹ iwọ yoo ri i pe o ti bọ́ sinu awọn ẹ̀ṣẹ ti o tobi ti o mu faaji ipalara nla lọwọ eyi ti o le mu ọkàn rẹ lọ sinu ijiya ayeraye. Lọ kuro ninu ẹ̀ṣẹ lonii. Bi iwọ kò bá yago fun ẹ̀ṣẹ, ẹ̀ṣẹ yoo pa ọ́.

Ni ibi diẹ leti òkun ni England ati Skọtland, o maa n digba ṣẹlẹ pe eniyan ti o n rin lori iyanrin yoo ri i pe lojiji iyanrin naa dabi ẹni pe o ṣe mọ̀dẹ̀mọ̀dẹ̀, a si ri i pe o n lẹ̀ mọ́ bata oun. Eti okun naa le dabi ibi gbigbẹ, ṣugbọn ipa ẹsẹ̀ rẹ̀ yoo kún fún omi. Eniyan tilẹ le maa rin lọ lai fura si ibi ti o wà niwaju rẹ̀. Ṣugbọn lojiji iyanrin bo ẹsẹ̀ rẹ̀ mejeeji. O yipada, ṣugbọn bi o ti n gbé ẹsẹ̀ ni kọọkan ni ẹsẹ̀ rẹ̀ n wọlẹ ṣinṣin si i. Pẹlu àya jijá, o ri i pe oun n rì sinu ilẹ rirọ̀. O sọ ẹru ori rẹ kalẹ, ṣugbọn o ti pẹ jù. Lai pẹ, iyanrin yii mu un de orúnkún, de ibadi, de igba-àya, de ọrùn. O figbe ta, ṣugbọn lai pẹ rara, iyanrin rọ́ kun ẹnu rẹ̀, a si pa a lẹnu mọ́. Lẹyin eyi, iyanrin bo o loju, oun a si ba ara rẹ ninu okunkun biribiri ti ikú! Ewu ẹ̀ṣẹ dida ti fara jọ eyi to! Ewu ti o wa ninu ẹ̀ṣẹ dida le má tete fara hàn bi ti ilẹ-iyanrin, ṣugbọn o lagbara bẹẹ gẹgẹ. Lakọkọ “okele didun,” lẹyin naa yoo di bárakú, ati lai pẹ rara yoo bá ara rẹ̀ ninu ewu takute ti n bo ni mọlẹ kiakia ti o si n rán ni lọ sinu iparun. Apá kan ṣoṣo ni o le ṣe iranwọ lakoko ajalu

yii; Ẹni kan ni o le gba ni là kuro lọwọ ikú. "Ki o si kepè mi li ọjọ ipọnju; emi o gbà ọ" (Orin Dafidi 50:15).

**Ere lẹyin Ijiya**

O jẹ́ iranlọwọ nla fun Paulu lati ni Oluwa titun yii, Jesu Kristi -- bẹẹ ni, Baba titun, ani Ọlọrun tikára Rẹ̀. Eleyi sọ Paulu di ajogun ijọba kan, bi o tilẹ jẹ pe diẹ ni awọn ohun ini rẹ̀ laye. Paulu mọ pe bi oun ba ba Jesu jiya nihin ninu ayé, a o ṣe oun logo pẹlu Rẹ̀ lọjọ kan. O mọ̀ wi pe "ade ododo" (2 Timoteu 4:8), n duro de oun.

Bi a ba jiya diẹ fun Kristi, ki ni o jẹ́? A kò le fi eyi ṣe akawe ogo ti o n bọ̀, ni Paulu wi. Nigbakigba ti o ba ni ero pe igbesi-ayé Onigbagbọ́ jẹ́ sisẹ́ ara ẹni kuro ninu jijẹ ọ̀pọlọpọ faaji ayé, fi inu ṣiro ohun ti Paulu wi: "Nitori ero ti ara ikú ni" (Romu 8:6). Nigba ti iwọ ba rò pe boya awọn eniyan ti ayé n jẹ igbadun faaji ayé ju iwọ ti o jẹ́ Onigbagbọ́, ronu nipa Paulu ti o wi pe: "Bi ẹnyin ba wà ni ti ara, ẹnyin ó kú." Ronu igbẹyin. Ronu ọjọ naa ti ẹni-giga, ẹni-rirẹlẹ, olowo, ati talaka yoo duro niwaju Onidajọ ododo. Nigba naa, ki ni yoo jẹ́ ipin awọn wọnni ti o n gbé igbesi-ayé wọn fun igba isisiyii nikan?

Iwọ wi pe, "ṣugbọn nigba ti mo ba pinnu lati sa ipa ju ti atẹyinwa lọ pẹlu ọ̀pọ adura, mo maa n ni wahala ti o pọ̀ ju igba ti mo wa ni ko-gbona-ko-tutu." Eleyi le jẹ́ otitọ, ṣugbọn iwọ yoo ni oore-ọfẹ ti o pọ̀ ju ti atẹyinwa lati la wahala wọnyii já. Paulu ti kẹkọọ pe ohunkohun ti o wù ki wahala tabi idanwo le jẹ "ohun gbogbo li o nṣiṣẹ pọ̀ si rere fun awọn ti o fẹ Ọlọrun" (Romu 8:28). Nitori naa bi Satani bá gbiyanju lati dán ọ wò ni ọna yii nipa fifi awọn ohun idigbolu si ọ̀na rẹ, iwọ sa wi pe: 'Mo le ṣai mọ idi rẹ̀ ti eyi fi dé si mi, ṣugbọn emi mọ̀ pe mo fẹ́ Oluwa pẹlu gbogbo ọkàn mi, Oun si fẹran mi, Oun kò jẹ́ fi àye silẹ pe ki eyi dé bá mi bi kò ba ṣe pe fun ire mi ni.'

**Ifẹ Kristi**

Paulu pari ori-iwe yii pẹlu ibeere ati idahun rẹ̀. "Tani yio ha yà wa kuro ninu ifẹ Kristi?" Wahala, airijẹ tabi airi aṣọ bora, ewu, ogun, ikú, iye, awọn angẹli, awọn alagbara, ọ̀na jijin tabi eniyan – kò si ọ̀kan ninu awọn wọnyii ti o le yà wá kuro ninu ifẹ Kristi. Ifẹ Rẹ̀ ki i yẹ lai.

Eyi ha tumọ si pe nigba ti eniyan ba ti ri igbala lẹẹkan kò tun le ṣubu kuro ninu oore-ọfẹ mọ́ ki o si ṣegbe? Bẹẹkọ, ki i ṣe bẹẹ rara. Otitọ ni pe ifẹ Kristi ki i yipada, ṣugbọn bi kò ba ṣe pe eniyan sun mọ Ọn girigiri nipa ṣiṣọna ati kika Ọrọ Ọlorun nigba gbogbo pẹlu ọ̀pọ adura, ifẹ eniyan si I le di tútù. Bi ifẹ oluwarẹ ba di tutu, ó wà lori ilẹ ti o lewu, nitori bi o ba ti n rin jinna si Oluwa tó, bẹẹ ni o n lọ sinu ayé tó, ati pe lai pẹ jọjọ kò tun ni jẹ́ ọmọ Baba mọ́. Lẹẹkan si i iṣudẹdẹ idalẹbi ọkàn yoo kún igbesi-ayé rẹ̀. Iwọ ha ti bọ́ lọwọ idalẹbi ọkàn?

**AWỌN IBEERE**

1 Ẹri ta ni a kọ silẹ ninu Romu 8?

2 Ki ni itumọ ririn nipa ti ara? Ririn nipa ti ẹmi?

3 Bawo ni a ṣe le mọ̀ bi a ba jẹ́ ọmọ Ọlọrun?

4 Ki ni itumọ ki a ya ni nipa kuro ninu ifẹ Kristi?

5 "Bi Ọlọrun bá wà fun wa, tani yio kọ oju ija si wa?"

6 Ta ni ohun gbogbo n ṣiṣẹ pọ̀ si rere fún?

7 Bawo ni àkawé ijiya ti Onigbagbọ́ nisisiyii ti ri pẹlu igba ti o n bọ̀?

8 Ki ni itumọ wiwà ninu ero ti ara? Wiwà ninu ero ti Ẹmi?